# IDANILEKO NIPA ARUN AIDS NI ILE UGANDA.

By Sarah Azia.

## ORO AKOSO:

Ni osu kesan odun 2000, ni ibi ipade gbogboogbo ni a ti se ipinnu nla lati din osi ati aini ku gidi titi odun 2015. Okan ninu awon ipinnu yi ni lati doju ija ko arun HIV/AIDS, arun iba, ati awon arun miran, ki a ba le mu igbega ba ilera awon eniyan to n gbe ninu aye.

## Eto ilera ni awon orile ede to si n dagba soke.

Osi ati aini le se idena fun eniyan lati je anfaani eto ilera, o si tun le dena eniyan lati ko ipa lati se atunto eto ilera awon ara ilu. Opo eniyan loti ku nipa ebi tabi aisan nitoripe won ko ni anfaani lati ri itoju to peye, ti won ko si ni aaye lati fi edun okan won han rara. Okan Pataki ninu awon isoro ti osi ati aini n fa ni wipe , a maa dena awon eniyan lati soro jade nipa awon aini won. Ni opo igba, a maa n ro wipe awon ti osi n da laamu ko le ran ara won lowo rara, bakan na a maa n fi awon orile ede to si n dagba soke si abe awon ase lai se ayewo awon isoro awon orile ede yi daradara. Riro wipe eniyan ko ni agbabara ninu ara re je okan ninu awon idena lati le gbe ninu alafia to peye, ati lati ri ona abayo kuro ninu ise. Awon ajo ile ifowo pamo ti agbaye si ti han wipe, o se Pataki lati ni oye nipa awon alaini, ati lati gbiyanju lati ran won lowo. O se Pataki lati ri wipe awon eniyan to n gbe ninu ilu ko ipa gidigidi lati se eto ilera awon eniyan won. Eyi je koko ohun ti o waye ninu eto idanileko to sele ni ile Uganda.

## IBASEPO TO WA LAARIN ARUN HIV/AIDS ATI OSI:

Arun HIV a maa fa osi wa. Opo ni owo ti eniyan maa padanu lati se itoju awon to ni arun yi, ti o fi kan owo ti a o fi sin oku awon ti arun yi ba gba emi won. Wahala ti arun yi maa n fa wa po gidigidi. Arun yi si n doju ko ilosiwaju, idagbasoke , ati eto oro aje opolopo awon orile ede ile adulawo. Awon alaini gan ni arun yi doju ko julo, nitoripe won ko ni ipa lati doju ija ko arun yi.Aini ilera to pe, ati iku a maa mu ki eniyan jin wo inu osi gidigidi. Awon alaini a maa se agbako arun yi gidi nitoriwipe won ko ni eko to ye kooro, aini aye lati fi ero okan won han, aini ise lapa eyi ti o le je ki won di agbero oko tabi asewo. Eyi a maa je ki iru awon eniyan bayi tete se agbako kokoro ti o n fa arun yi. Aini onje to dara lati je, nini awon arun miran ti a maa n ko lati ibi ibalopo, je awon ohun miran to le je ki kokoro yi tete ri aye wo ara eniyan.

Gegebi arun HIV se le fa osi ba eniyan, bakanna osi a maa tete fa arun yi ba ni.
Arun HIV a maa so eniyan di edun arinle. A ni lati doju ija ko arun yi gidi ki a to le bori osi laarin awon eniyan to n gbe ni awon igberiko.

## KI NI KOKO IDANILEKO YI?

Pataki ohun ti idanileko wa fun ni ki a baa le se edinku awon ti o n fi ara ko arun HIV, ati lati le se itoju to peye fun awon to ti ni arun yi. A ni lati wa ona lati se idanileko lori ibalopo laarin okunrin ati obinrin ni opo awujo wa..
Ipa meta ni idanileko yi fi han eyi ti a fi le din kiko arun yi ku ni awujo wa.
Ipa kini ni lati sa fun ibalopo patapata, tabi ki a sun bibere ibalopo si iwaju.
Ipa keji ni wipe a ni lati je olooto si enikeji wa, ki a si ko agbere sise sile.
Ipa keta ni wipe, a ni lati maa lo roba ni igba ti o baye, papa ti a baa fe ni ibalopo pelu awon ti o sese ki wo ti ko arun yi.
A ni ero wipe awon ona wonyi maa ran wa lowo lati se edinku awon ti arun yi n so di olosi.

## ETO IDANILEKO NI ILE UGANDA:

Eto idanileko yi ti gbile gidi nitoriwipe eto naa ti ran awon eniyan ile naa lowo lati dekun ajakale arun HIV. Awon eniyan to ni arun yi ti dinku gidi ni ile Uganda laarin odun 1991 si 1998.
Ohun kan Pataki ti o mu edinku yi wa ni bi awon eniyan ile naa se din sise agbere ku, ti opo won si bere si lo roba ni igba ti won ba ni ibalopo. Opo eniyan ti so wipe aseyori ti orile ede Uganda se waye nitoriwipe won sa ipa ti won ni lati ri wipe awon eniyan yi iwa won pada, ti won si n lo gbogbo ona lati dena arun HIV.
Opo awon ewe ile naa ni won bere si ni ko ara won ni ijanu nipa ibalopo, sise agbere din ku , ti opo awon eniyan sib ere lati ma lo roba ni akoko to ba ye.
Aare ile naa, Museveni, ati awon ajo miran sis a gbogbo ipa ti won ni lati doju ijha ko ajakale arun HIV. Awokose yi lo si mu iyipada pade ile naa.
Ki a to le ni oye idi ti ile Uganda se se aseyori mimu edinku ba ajakale arun HIV, o ye ki a se atuwo awon ohun ti a ni ero wipe o fa osi wo ile naa, ati ibasepo ti won ni pelu idanileko ti a se nipa arun HIV. Aare ile naa, Museveni gba ona oto lati gbogun ti arun HIV. Kaka ki aare Museveni gba ona ti opo eniyan ti maa n gba lati doju ija ko arun yi, aare naa pinnu lati bere awon eto eyi ti o maa yi iwa awon eniyan pada si rere, ni Pataki ni ipa ibalopo, a sit un bere si ni se ipologo nipa arun AIDS.

## SISE AGBEYEWO ETO LATI DENA ARUN HIV:

Awon ipile kan wa ti ile Uganda fi le ile ni igba ti won se agbekale eto lati dena arun HIV. Bi a ti fi han li akoko, arun HIV le se okunfa osi, bakanna osi le fa arun yi ba eniyan. Nitori idi eyi, ki a to le din osi ku ni awon igberiko wa, a ni lati ri wipe a sa ipa lati mu edinku ba iye awon ti o n ko arun HIV, a si ni lati pese itoju to peye fun awon ti won ti ko arun yi. Ile Uganda je akoko ni gbogbo agbaye lati se agbekale eto lati doju ija ko arun HIV. Aare Museveni bere awon eto yi ni kete ti o gun ori aleefa ni odun 1986. Ile Uganda je akoko ni Afirika lati se ibapade arun AIDS ni odun 1982. Ni odun 1980, Uganda je okan ninu awon orile ede to ni arun ju lo ni agbaye. Lehin bi odun mewa, ile Uganda je okan ninu awon orile ede ti arun HIV ti n pa eniyan ju. Ile naa je alaini gidi,

eyi tie to oselu won ko si fi ara ro rara.. Bi enuiyan tip o to ni ile naa, opo awon eniyan ko ni imo iwe to ja gaara, eto ilera won ko se dede, ti opo won si n ku li ewe. Bi o ti le je wipe awon isoro wonyi n ba ile Uganda fira, sibe arun HIV bere si ni dinku ni odun 1990. Ni okan ninu awon ilu igberiko ni ilu Uganda, arun yi dinku gidi laarin odun 1990 si 1998.
N je a le so wipe eto idanileko yi lo fin edinku yi ba ile Uganda? N je eto yi le se aseyori ti a bamu okan kuro lara awon ipa meta ti eto na pin si? A o se agbeyewo awon ibeere wonyi ki a le ni imo to jinle si nipa eto idanileko naa.
Awon alaini ni awon igberiko ko ni anfaani lati fi ero okan won han, eyi si je idiwo fun won lati tuna aye won se ni awujo wa.
Okan ninu awon ona ti aare ile Uganda gba ni lati fun awon obinrin ati awon ewe ni anfaani lati ko ipa gidi ni awujo won, to bee ge ti ida kan ninu meta awon asofin ile naa je obinrin.
Awon obinrin si ti ja takuntakun lati ri wipe awon obinrin ni aaye to dara ni awujo. Nipa ise ti awon obinrin se li o je ki a se awon ofin eyi ti o n daabo boa won obinrin lowo ilokulo, ti o si n fun won ni awon eto won.

A o fi han laipe wipe awon odo, ati awon obinrin,ni Pataki, ni arun HIV tete maa n ko lu ju. Arun HIV ko ni dekun ati maa baa won eniyan ja afi ti a bam u igbega ba igbesi aye won. Fifun awon odo, ati awon obinrin ni agabra yio mu edinku ba kiko arun HIV, eyi ti yoi si mu edinku ba osi ati ailera.
Ajakale arun HIV tip e ni ile Uganda. O si pe ti awon eniyan ti n ku lati owo arun eyi ti o maa n je ki awon eniyan gbe titi won yi o fi ku. O to odun 1982 ki a to mo wipe arun HIV ni o n pa awon eniyan wonyi. Eyi fi ye wa wipe , ni akoko to eto lori didekun arun HIV bere ni odun 1987, opo awon eniyan ti ni oye wipe arun ti o buru gidi li arun HIV. Nitori idi eyi, opo awon omo ile Uganda se akiyesi eto yi nitoripe opo awon eniyan ni arun yi ti se iku pa. Eru ba won nitoripe won mo wipe arun yi le fa osi gidi ba ile won. Eto idanileko yi ni a si lo lati ri wipe edinku ba ajakale arun yi ni ile Uganda. Ile Botswana gba awon ona ti Uganda gba lati doju ko ajakale arun HIV, sugbon won ko se aseyori kan kan. Awon eniyan li ero wipe, ile Botswana ko fun awon eniyan won li aye lati ri wahala ti arun yi le ko ba eniyan ki won to bere eto won.
Awon aheso oro li orisirisi li a lo lati se idanileko yi. Awon aheso oro wonyi si je ohun ti awon eniyan ile Uganda le tete ni oye won, to bee ti awon eniyan igberiko ko li isoro lati ni oye ohun ti awon oro wonyi tumo si.
A ko koko soro nipa lilo roba fun ibalopo eyi ti ile Botswana se. A soro lori fifi iwa agbere sile gege bi ona lati dena ajakale arun HIV. Idanileko ti ile Botswana ko se aseyori nitoripe won ko tara lati ma kede lilo roba fun ibalopo,bakanna ede ti won nlo lati se idanileko won yi ti awon eniyan ko ni ife si rara.
Aare ile Uganda ko tara lati bere si ni kede lori lilo roba fun ibalopo eyi ti aare ile Botswana se. I di ni wipe, aare ile Uganda gbagbo wipe sise ikede lori lilo roba fun ibalopo yio je ki iwa agbere wopo laarin awon eniyan, eyi ti o si lodi si eko esin.Aare Museveni gba lati bere ikede lori lilo roba leyin akoko die. Ni akoko yi , opo awon eniyan ile naa li o ti ri awon wahala eyi ti arun HIV le fa wa, eyi si mu ki awon eniyan ri anfaani nla to wa ninu lilo roba fun ibalopo. Bi o ti le je wipe aare ile Uganda bere si ni se ikede lori lilo roba, aare yi gbagbo wipe aseyori ti ile naa se ro mo idanileko ti won se lati lodi si iwa agbere li awujo won. Aare Museveni te enu mo wipe lilo roba ki se ona ti

o dara julo lati dena arun HIV. Li otito , opo eniyan gbagbo wipe lilo roba se iranwo gidi lati dena kiko arun HIV, sugbon opo awon ojogbon gbagbo wipe kiko iwa agbere sile li o se Pataki julo lati dena kiko arun HIV.
Ti o ba je otito wipe kiko iwa agbere sile li o se Pataki julo lati dena kiko arun HIV, ki ni idi ti a ko se yo lilo roba kuro ninu eto ile Uganda lati dena arun HIV?

Ni ile Afirika, eyi ti awon ti arun HIV n ba ja po si gidi, o soro lati so pato bi awon ti o je abileko se je olotito si enikeji won to. Awon obinrin ti o je awon nikan li oko won fe papa le tete fi ara ko arun yi , idi ni wipe won ko le ko oro si awon oko won lenu. Nitori idi yi , a ko le mu lilo roba kuro ninu idanileko lati dena arun HIV. Mimu lilo roba kuro ninu eto idanileko yi yio je ki opo awon ewe, papa julo awon obinrin fi ara ko arun HIV. Nitoriwipe arun HIV le fa osi ba eniyan, o di dandan lati se ohun gbogbo lati dena kiko arun yi. Sise eleyameya ko li ohun kan lati se lati dena arun HIV. O se Pataki ki gbogbo eniyan mo nipa ona lati dena arun HIV, a si ni lati se ikilo fun awon eniyan nipa awon ona ti a se le ko arun HIV. Awon eniyan ti n bge ni igberiko li arun yi le tete je ni iya julo, nitori arun yi ko ni fun won ni aaya lati se ise oko won bi o ti ye ati awon ise miran. Bakanna won ko ni anfaani lati ri itoju to peye. A ni lati se ipolongo kiko iwa agbere sile , ki won si maa lo roba bi o ti ye ki a ba le deana kiko arun HIV.
O seni laanu wipe ijoba aare Bush n se iranwo fun awon eto to n polongo kiko iwa agber sile , ti o si yi lilo roba kuro patapata. Eyi si je ohun ti o se atona awon eto idanileko li ile Uganda. Bakanna aare Bush n te siwaju lati tepele mo kiko iwea agbere sile, ti o so lodi si oyun sise gidigidi. Eyi le ni se pelu sis ease yori pelu eto idanileko ile Uganda li ojo iwaju.
Biba ara eni soro je okan ninu awon ohun to mu aseyori ba ile Uganda. A ni lati gbe osuba fun aare Museveni lori aseyori yi. Lati ibere ijoba re li ko ti dekun lati doju ija ko arun HIV. O lo akoko lati se ifikuluku pelu awon omo ile Uganda, no fi han wipe awon omo ile naa ni lati se ise takuntaku lati gbogun ti arun HIV.
Aare Museveni se agbateru idanileko eyi to kari ibi gbogbo ni ile naa, o se amulo awoniwe iroyin, ero asoromagbesi, ati bebe lo.
Aare yi sise pelu awon adari ile naa lati ru awon eniyan soke lati bere si gbe ogun ti ajakale arun HIV.
Ni ipase eyi ni opolopo awon eniyan ni imo nipa arun HIV. Nitoripe awon olodanni li o n se ise lati gbogun ti arun yi, eyi ran idanileko naa lowo gidigidi. Eyi ran awon eniyan lowo lati yi iwa won pada, bi o ti le je wipe awon eniyan naa sese n bo lowo iya to n je won leyin ogun abele ti o ja ile naa.

## Oro ipari:

Se idanileko yi se aseyori lati dekun titan kale arun HIV bi, ati lati se itoju to peye fun awon ti arun yi n baja?
A le so daju wipe , sise edinku titan kale arun yi ti je aseyori. Ise takuntakun ti aare Museveni ati awon omo eyin re se si je idi kan pato eyi ti a fi dekun itankale arun yi. Sise ifikuluku, ati sise idanileko lati yi iwa awon eniyan pada si rere pelu je awon ipa ti a ko lati dekun arun HIV, ati lati pese itoju to peye fun awon ti arun yi n yo lenu ni ile Uganda.

. Ki ni ibasepo to wa laarin osi ati awon eto awon ijoba wa? Bi a ti fi han siwaju, aini ilera to peye, aini ime eko to mu ina doko, aini anfaani lati fi ero okan eniyan han, ati aini anfaani lati ri itoju to peye, je awon idi ti osi fi wopo ni awon igberiko wa.
A fi han wipe ibasepo wa laarin eto awon ijoba ati osi ni ile Uganda.
Gege gi ona lati ri wipe awon eniyan ri anfaani lati fi ero okan won han, ijoba ile Uganda se eto lati fi agbara fun awon ewe ilke naa, ati awon obinrin ile Uganda.
Bakanna ,a gba awon eniyan niyanju lati kopa ninu gbigbogun ti arun HIV, eyi to si je ki ipo ilera awon eniyan lo siwaju. A tun ran awon eniyan lowo se awon eto nipa arun HIV.
Awon ti won si n se ise to le tete fa arun HIV wa li a gba niyanju lati bere si lo roba ni akoko ibalopo. Eyi ko ipa lati se edinku kiko arun HIV.
Li akota, eto idanileko ti a lo ni ile Uganda se aseyori gidi nitoriwipe awon eto naa baa won eniyan ile na lara mu gidi. Eyi si se edinku ijiya awon eniyan igberiko.
Bi o ti wu ki ori, eniyan ko le so pato wipe a ti segun arun HIV patapata. Eto ile Amerika eyi ti o yo lilo roba kuro je ohun to ku die kaato. O je ipenija fun ile Uganda lati wa ona lati parowa si ijoba ile Amerika lati gba wipe lilo roba je ona kan Pataki lati dekun itankale arun HIV.
A ri eko nla lara ona ti ile Uganda gba lati dekun arun HIV, sugbon eyi ko so wipe gbogbo ibi ni iru eto bayi ti le se aseyori. Ile Uganda wa ona to ba ile naa mu lati gbogun ti arun HIV, ona ti o ba asa ile naa mu.
O ye ki orile ede kookan wa ona lati se idanileko lati gbogun ti arun HIV ni ile won, sugbon opo ni ogbon ti a le ko lati ara aseyori ile Uganda.

Translated into Yoruba Language by:
Dr ADEOTI , Abolaji
Pretoria,South Africa
28. Dec. 2007.